**SECOND TERM**

**YORUBA LANGUAGE SS ONE**

ETO ISE FUN SAA KEJI

| | |
|---|---|
| Ose kin-in-ni | Ede-Atunyewo awon isori oro ninu ede Yoruba |
| | Asa:Elegbejegbe tabi iro-siro |
| | Litireso: Itupale iwe aseyan ti an ka |
| Osa keji | Ede-Awon isori gbolohun ede Yoruba gege bi ihun |
| | Asa: Asa iranra-eni lowo |
| | Litireso: kika iwe litireso ti ijoba yan |
| Ose keta | Awon isori gbolohun Yoruba gege gi ise won |
| | Asa: Itesiwaju ninu asa iranra-eni lowo |
| | Litireso : kike iwe litireso ti ijoba yan |
| Ose kerin | Ede-Aroko asapejuwe (ilana) |
| | Asa: oge sise(1) |
| | Litireso: kika iwe litireso ti ijoba yan |
| Ose karun-un | Ede- Akanlo ede |
| | Asa : oge sise (2) |
| | Litireso : kika iwe litireso ti ijoba yan |
| Ose kefa | Ede- sise aayan ogbufo |
| | Asa: Igbeyawo ibile |
| | Litireso: Kika we litireso ti ijoba yan |
| Ose keje | Ede-sise aayan ogbufo |
| | Asa: igbeyawo ni ile Yoruba, orisi igbeyawo ti o wa |
| | Litireso: kika iwe litireso apileko ti ijoba yan |
| Ose kejo | Ede-onka ede Yoruba ookan de egbaa (1-2000) |
| | Asa: Asa igbeyawo |
| | Litireso: kika iwe litireso ti ijoba yan |
| Ose kesan | Ede- Atunye eko lori |
| | Asa: Oyun ninu, itoju ati omo bibi |

| | |
|---|---|
| | Litireso : Itan oloro geere bii; orisunn itan ati asa Yoruba |
| Ose kewaa | Ede- Aroko asotan oniriyin |
| | Asa: Asa isomoloruko |
| | Litireso: Alo apamo ati apagbe |
| Ose kokonla | agbeyawo ise saa keji |
| Ose kejila | Idanwo Ipari saa keji |

**Ose kin-in-ni**

**Akole ise: Ede- Atunyewo**

Isori oro ninu ede Yoruba

Isori oro ninu ede Yoruba ni wonyii

i. Oro-oruko
ii. Oro Aropo oruko
iii. Oro Aropo Afarajooruko
iv. Oro Eyan / Apejuwe
v. Oro Ise
vi. Oro Aponle
vii. Oro Atokun
viii. Oro Asopo

Oro-oruko: Eyi ni awon oro ti won le da duro ni ipo Oluwa, abo tabi eyan ninu gbolohun. Ipo meta ni oro oruko le ti jeyo ninu gbolohun. Awon ni ;

a) Ipo Oluwa :- Eyi ni oro oruko ti o jeyo ni ibere gbolohun tabi ti o je oluse isele inu gbolohun. Apeere ;

   <u>Sola</u> lo si iwo

   <u>Ade</u> jeun yo

   <u>Alaafia</u> to oyo

b) Ipo Abo :- Eyi ni olu faragba nnkan ti oluwa se ninu gbolohun. Aarin tabi ipari gbolohun ni o maa n wa. Apeere ;

Oluko ra <u>oko</u> ni ona

Jide gun <u>iyan</u>

d) Ipo Eyan :- Ti oro oruko meji ba tele ara ninu apola oruko, oro oruko keji ni yoo yan oro oruko kin-in-ni. Apeere ;

Olumide <u>oluko</u> ti de

Iwe <u>iroyin</u> dara lati maa ka

Eja <u>alaran-an</u> ni mo fe ra.

Oro oropo-oruko :- Orisi ipo meta ni oro oropo-oruko ti le je yo ninu ihun gbolohun ede Yoruba.

A. Ipo Oluwa :-

| Eni | Eyo | Opo |
|---|---|---|
| Kini | mo | A |
| Keji | O | E |
| Keta | O | Won |

i. O le je yo saaju oro-ise nipo…